# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 896 LAGOS SATURDAY NOV, 23 — NOVEMBER 29 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


# Awon Olopa Tu Asiri Mo Awon "Oyinbo" India Atepali Lori

DELHI A ṣe ko si ibiti awọn oniwayo "ATẸPALI" ko si! Irohin nla kan ti a gbọ lati ilu awọn India ni alẹ ana nipa awọn onişẹ madaru ti awọn Ọ ọpa India gba mu ninu igbo kiiikiji nibiti nwọn gbe ti ntẹ iwe-(aşẹ passport) lati mu lọ si ilu Gẹsi (England) ni o jẹ ki a wi bayi.

Gẹgẹbi waya iwe irohin ti a ri gba nipa awọn oniwayo India na, nwọn ni Jullunder ni agbegbe Punjab ni awọn na gbe ẹrọ itẹwo ti nwọn fi ntẹ awọn iwe aşẹ irinrinajo (passport na si.

Nwọn ni igba ibusọ ni igbo na fi jinna si Ariwa Delhi orişi adamọdi iwe-aşẹ ti nwọn ti tẹ ni awọn Ọlọpa ti nwọn lọ ko awọn ri ko nibẹ, nibu awọn iwe adomọdi ti nwọn ti tẹ na ni nwọn gbe ti ri awọn iwe itiwọşẹ na gbagbagba pẹlu orukọ awọn ọga eyibo ile işẹ ti aşogun Ọba Gẹsi ti o wa awọn iwe adamọdi na.

A gbọ wipe o to ẹdẹgbẹtẹ pọnun (£500) ti wọn nta ọkọkan iwe adamọdi na funawọn ara ilu India ti nwọn nfẹ lọ şe işẹ nilu Oyinbo. A tun gbọ wipe awọu ti nwọn ti fi owo wọn ra iwe aşẹ irinajo na ti iu ẹgbẹ mẹdọgbọn (5,0000) enia lọ sinu awọn ara ilu Pakistan ti nwọn si lọ wọ işẹ ni London ati Birmingham.

Awọn Ọlọpa ni awọn ko ti mọ ọna ti awọn yio fi le da wọn pada silu wọn

## Awon Ara Loko Pe Loya Ti Nwon Ran Lo Si Ilu Oyinbo Lejo

EKO—Lọya agbẹjọro ti Ijọba kan ẹniti orukọ rẹ njẹ Luku Emejulu ti awọn oşişẹ ọgba reluwe ni Loky fi igba kan fi owo ẹgbẹ wọn ran lọ si ilu Oyinbo lati kọ işẹ agbẹjọro (lawyer) ni a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ na pe lẹjọ wipe ki o wa san owo ti awọn fi ran an lọ kọ ẹkọ ni ilu Ọ ba.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

CHRISTMAS MEETING, 1963/64
SUNDAY 22ND. THURSDAY 26TH, SUNDAY 29TH DECEMBER, 1963, WEDNESDAY 1ST AND SUNDAY 5TH JANARY, 1964.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P.O Box 51, Lagos or at the Race Course Lagos.

Note – No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 9th December, 1963.

No Cheque will be accepted.

C. H. E. MILLER
Hon: Secretary


### "Obi Ni A Ri Bawi"

# Oro "Aloyun Kawe" Wa Ni Kotu

( Wo yoku loju ewe kejọ )

EKO— Bashiru Bada, ọmọ ọdun mejilogun, ti awọn Ọlọpa ni o fẹ şẹ oyun fun ọmọ ilewe kan, Silifatu Arekemaşe ti o nlọ si ile iwe Ebute - Ero ni a gbọ wipe awọn ọlọpa mba şẹjọ lọwọ lọwọ lori ọrọ oyun oşu mẹta ti nwon fẹ şe na.

Ọmọge Salifatu Oloyun na ni o kọ bọ sinu apoti ti o ro ẹjọ ni ijẹta. o ni iiewe ni on wa ti Bashiru fi fun on loyun o, o ni on ni ko jẹki on le ka iwe on yori. O ni on niran ọjọ ti Bashiru mu egbogi kan wa wipe ki on lo o nigbati on sọ fun wipe on loyun fun un.

Salifatu ni nigbati on lo egbogi na on fẹ yọ sọrun alakeji nitoripe nşe ni on npọ jẹ ti on si obi ebi, şugbọn baba onişegun kan ti Bashiru tun pe wa ni ni o sọ fun on wipe ki on ye lo egbogi ti o mu wa na.

Adajọ Ọgbeni O. Olaoye ti nwọn nro ẹjọ na niwaju rẹ wa bi i lere bi lọdọ awọn obi rẹ lo gbe ngbe ti o

( wo yoku loju ewe kejọ )

## Ijoba Ilu Congo Le Awon Russia Kuro Nilu Won

CONGO-(BRAZZAVILL)-Awọn alamojuto Ijọba ilu Kongo (Congo) ti faake kọri wipe ki gbogbo awọn Oyinbo ara Rọşia (Russia) ti Ijọba ilu na ran lati Moscow, olu ilu Russia, wa si Kongo gẹgẹ i aşoju Ijọba ilu na pale wọn mọ, ki nwọn si kuro nilu awọn lọgan nitori iwa wọn ko batawọn mu rara.

Irohin ti a kọ gbọ nipa ọrọ awọn Oyinbo Rọşia ti o wa nilu Congo ni ti awọn meji ti awọn ọlọpa ọ tẹ̀ ... ẹ gbamu.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Awon Omo Egbe Ibo Lo Si Kotu Tomotomo

KADUNA — Gbogbo awọn Ibo ti mbẹ ni ilu Kaduna ni nwọn lọ si kotu awọn Ọlọpa ni ijẹta tọmọtọmọ ati awọn aya wọn lati lọ gbọ ẹjọ ti awọn ọlọpa fẹ ba awọn olori ẹgbẹ wọn ro lori ipade nla kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ṣe lalpẹ yi.

Ọgbẹni Ibo onimọto kan ti o njẹ Luke Ejinkeonye pelu awọn meje 'kan ni awọn Ọlọpa mba ṣe ẹjọ wipe nwọn ṣe ipade ẹgbẹ wọn nita lai gba iwe-aṣẹ lọwọ awọn ọlọpa.

Ni ijẹta ti nwọn bẹrẹ si ro ẹjọ wọn, ṣe ni kotu kun bamubamu fun awọn onisowo Ibo, gbogbo awọn ti nta nkan lọja ni nwọn pa iṣẹ wọn ti, ti wọn ko lọ s'ọja.

Awọn Ijoba paapa ko fikan po meji nṣe ni nwọn ko awọn ọlọpa onikunmọ wa si kotu boya a le ri ẹniti O fẹ da ijangbọn silẹ lori ọrọ na.

Nwọn koiti pari ẹjọ rirọ na.

THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA, ONITSHA.

Sub-Distributors:—

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.

## Itan Ore Meji

Lati Ọwọ MOSHOOD BURAIMOH

Ni igba kan awọn ọrẹ meji 'kan wa, awọn mejeji se ileri pe awọn ko ni da arawọn.

Ni igbati o di ijọkan, awọn mejeji lọsi oko ọdẹ. Ni igbati wọn de oko ọdẹ beni ẹkun kan yọ si awọn mejeji lojiji, aya awọn mejeji ja ikan si sare gun igi kan lọ. Ni igbati ekeji ko mọ ohun ti on yio ṣe, o sare dọbalẹ kiakia o si sẹ ẹmi. Ẹkun yi si fi imu run ara ọgbẹni ti o dọbalẹ yi, o si ba ọna tire lọ.

Ni igbati eyiti o gun igi sọ kalẹ o bi ọrẹ rẹ lere pe " kini Ẹkun yẹn ba ẹ sọ "

Ẹnyin okawe mi, kini ẹ ro wipe kinni o ti daa lohun ?

Pẹlu ẹrin ni o fi da ọrẹ rẹ lohun, o ni o sọ fun on pe ki o maṣe gba ọrẹ rẹ yi gbọ mọ, nitoripe ọrẹ ododo ni lati duro ti ọrẹ rẹ ni nigbati isoro tabi ewu ba de·

Ẹnyin ara mi bi ẹ ba wo inu aiye ti a wa yi kakiri ẹ o ri wipe iru awọn ọrẹ afojufeni bayi pọ larin wa lọkunri ati lobinrin.

Bi nkan buruku ko ba ti de ba ọ, wa ṣebi gbogbo awọn araiye ni nwọn fẹran rẹ, bi idanwo nla ba de ni iwa to mọ wipe awọn ti o o ;npe lọrẹ atata kiṣe ọrẹ rara.

# E Polo—wo Oja Yin Sinu

# Iwe Irohin Eleti-Ofe

### Olofintoto Ni :

# Owo - Bode Pa Aso Aloku Lori

Ninu oṣu September ti o kọja yi ni awọn alamojuto eto inawo Ijọba gbe ofin tuntun kan jabe lati bu owo-bode kun owo aṣọ aloku ti awọn onişowo kan nko wọlu. Owo-bode na ti awọn alamojuto eto inawo Ijọba bu si bode ni fẹrẹ da ijangbọn silẹ awọn oniṣowo aṣọ bọsikọna ni ilu Aba ati Port-Harcourt. Nwọn ni o dybi ẹnipe Ijọba fẹ ba owo aṣọ-aloku na. ẹ mọ awọn lọwọ.

Şugbọn nigbati emi Olofintoto bẹrẹsi wa idi ọrọ na kiri, akan ti mo gbọ ya mi lẹnu pupọ Mo gbọ wipe awọn ọrẹ wa ni Ipinlẹ Ila Orun ti wọn nşe owo aṣọ bọsikọna ni nwọn nlo wayo fun Ijọba.

## Owo Bode

Mo gbọ wipe awọn ti o nranṣẹ fun awọn aṣọ na ni ilu Oyinbo ni ọgbọn arekereke kan ti nwọn nlo fun awọn akọwe - bode ki nwọn ba mọ san owo pupọ lori aṣọ aloku na.

Ọkan ninu awọn akọwe bhde fi ye mi wipe bayi ni awọn onişowo aṣọ na nşe. Nwọn ni awọn aṣoju kan ti nwọn fi si ilu Oyinbo, awọn aṣoju yi ni yio ra ẹru aṣọ aloku ni ọja fun wọn. Bi nwọn ba ti ndi awọn ẹru na ni nwọn a ma nu awọn aṣọ-tuntun dẹ diẹ ha wọn.

## Aṣọ Tuntun

Owo-bode ti awọn ni lati san lori awọn aṣọ aloku BỌSIKỌNA wọnyi kere pupọ si eyinti nwọn ni lati san lori awọn aṣọ tun tun. Awọn alaṣọ aloku nwọnpi mọ irun ipalara ti awọn nfẹn Ijọba nitoripe gbogbo ara ilu Nigeria ni nwọn nja lole.

Eyi ni o mu ki minista alamojuto eto inawo Ijọba apapọṣe, Oloye Okotie-Eboh ba Ijọba damọran wipe ki nwọn fi owo bode kun owo ti wọn ti nsan lori aṣọ aloku.

Mo gbọ wipe gbogbo aṣọ aloku ti awọn Ibo nko wọlu, ọna bode Pọta (Port-Harcourt) ni nwọn eko wọn gba. Laipẹ yi, nigbati Ijọba fi owo-kun owo-bode awọn aṣọ na, ọkẹ kan ati abọ (30,000) ni okiti ẹru aṣọ aloku ti o wa ni bode ti nwọn ko wa gba rara.

## Bode Kun

Lati ebute Pọta yi ni awọn yio ti ma ba awọn okiti ẹru aṣọ wọnyi lọ si ilu bi Aba, Onitsha, Enugu Umuahia, Kano Jos, ati Kaduna. Diẹ diẹ ninu awọn aṣọ na ni nwọn nko wa si Eko ati Ibadan nitoripe awọn Yoruba ko fẹran ara aṣọ aloku rara.

## Iwe Wayo

Ọna miran ti awọn alaṣọ aloku na tun ma ngba şe işe wọn ni ki nwọn sọ wipe ki ẹniti o fi ẹru na şọwọ ṭe iwe - ọna (invoice) meji: ọkan yio sọ iye ti ẹru na jẹ, ọkan yoku a jẹ ti oni-wayo ti awọn yio din owo ẹru na ku, ki nwọn ba ma le san owo-bode ti o pọ lori awọn okiti aṣọ na.

---

# Awon Ara Isheri Fe Ko Olofin Loba

ABẸOKUTA—Gbogbo awọn ara Isheri faake kọri, nwọn ni awọn fẹ ki Ijọba ba awọn yọ Ọba awọn, Ọba Salami Ayọdele tişe Ọlọfin Isheri, nwọn fi iwe-ẹbẹ ọrọ na ranşẹ si awọn Igbimọ Ijọba ibilẹ Ẹgba ni Abẹokuta, nwọn si tun fi ẹda iwe-ẹbẹ wọn na ranşẹ si Ọba Adeshina Gbadebọ Keji, Ọba Alake. ti o şeşẹ gun ori itẹ.

Ni ijẹta ni awọn igbimọ Ẹgba yan awọn enia mẹrin pataki kan lati şe iwadi nkan ti o faa ti awọn ara Isheri fi fẹ kọ ọba wọn na. Ọba Adeọshun, Agura ni yio şe alaga iwadi na.

Irohin kan ti a tun gbọ lati Ipinlẹ Iwọ Orun wa ni ti iwe ti awọn ara ilu Ọrangun fi ranşẹ si awọn alamojuto eto oye ro ọrọ Ọba awọn, ki nwọn fi oriọ-ọba ti nwọn npe ni William Apeni jọba Ọrangun, on ni awọn nfẹ lọba.

---

## Aropileni Jalule Ninu Dahomey: Enia Merin Loku Sibe

COUTONOU Awọn enia mẹrin ni nwọn ku bamubamu ninu ọkọ ofurufu kan ti o ja lulẹ ni ilu Contonon ni ale ana. irohin ti a gbọ nipa ijamba na ni wipe o to oşu mẹrin gbako tisisiyi ti ọkọ ofurufu na ti npara ilu Dohomey fun işẹ pataki kan lati ilẹ Nigeria.

Nwọn ni lati Kano ni ọkọ na ti gbera, o si de ebute Contonon ni alafia şugbọn bi o ti fẹ gunlẹ ni o tun sare gba okun lọ ki o to jabọ nibẹ. A ko ti mọ orukọ awọn ti o ku sinu ọkọ ofurufa na ati wipe awọn Oyinbo ni awọn ti o wa nibẹ nwọn kişe enia-dudu rara.

---

## Ijoba Ti Nko Awon Elewon Kiri

ILESHA — Ija ojojumọ ti o mbẹ silẹ larin awọn ẹlẹwọn ninu ọgba ẹwọn ni Ilesha ti jẹki Ijọba faake kọri wipe ki awọn dẹrẹba gbe awọn ẹlẹwọn ti o ba ya akọ lọ si ilu miran.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, o to ọgọta awọn ẹlẹwọn ti nwọn ti gbe lọ si ilu miran lati Ilesha nisisiyi. A gbọ wipe ọpọlọpọ wọn ni nwọn mu lọ si Enugu ati Kakuri Kaduna.

Onirohin wa fi ye wa wipe awọn ẹlẹwọn nikan kọ ni awọn kokuro ni Ilesha, nwọn tuu ko awọn dẹrẹba ọga wọn pẹlu lọ si ilu miran.

Ninu ọdun yi nigbati awọn ẹlẹwọn da rogbodiyan silẹ, nwọn pa ọkan ninu awọn ẹlẹwọn na ti orukọ rẹ njẹ Kọlawọle Afọlabi ni apẹfọn.

Onirohin wa ni nwọn ti yan awọn Ọgbeni N. Boyle, Igbakeji ọga agba awọn dẹrẹba ati Ọgbeni G. Amobi, ọga dẹrẹbẹ pe ki nwọn wa di akan o fa ti awọn ẹlẹwọn Ilesha na fi ma nja nigbakugba. Nwọn si ti bẹrẹsi gba ọrọ lẹnu ọpọlọpọ awọn dẹrẹba ati awọn paapa ki rogbodiyan miran to bẹ silẹ.

---

E ma ka

Iwe Irohin

Eleti-Ofe

Losose

O kunfun irohin aladun.

# ELETI-OFE

( ANJU WỌN KOSE WI LẸỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS: 28, Kosoko Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAMS: "ELETI-OFE" LAGOS
Phone 23370

VOL. XIV. No 1'6 SATURDAY NOV. 23 - NOV 30, 1963

# E Ka

**Oro AYILUKA loju ewe Karun Ti o kun fun oro Ologbon pelu Oye**

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, inà-titàn ati lati mã fi yánà, Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

# Iwe Si Olotu

## Ni Ilu Oyinbo: Dokita So Awon Obinrin D'Agan

HANOVER (PRUSSIA). Ọwọ awọn ọlọpa tẹ dokita ọjọgbọn kan ti orukọ rẹ njẹ Dokita Axel Dohrn ti a gburo wipe o ni egbogi pataki kan lọwọ ti o fi nṣọ awọn obinrin di agan.

A gbọ irohin wipe awọn ọlọpa ilu Hanover ni Prussia lẹba Germany ti mu dokita na lọ si iwaju adajọ pelu ẹsun wipe o sọ adajọ awọn obinrin dagan nilu.

Awọn ọlọpa ni nigbati nwọn ru dokita na de iwaju adajọ on funra rẹ ni o jẹwọ wipe ẹsun kekere ni nwọn fi sun on. Dokita Dohrn ni larin ọdun mejila o ju ọgọrun din lẹgbeje (1,300) awọn obinrin lọ ti on sọ dagan.

Dokita na ni awọn obinrin funra wọn ni nwọn ntọ on wa wipe awọn ko fẹ bi ọmọ mọ.

## Awon Egbe NPC Bu Enu Ate Lu Oro NCNC

KALUNA—Ija nla kan fe be larin awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu meji, awọn ọmọ ẹgbẹ Olcmi ati ẹgbẹ Alakuko; ti nwọn mba ara ṣe Ijọba apapọṣe pọ ti nwọn nṣe l'Eko, lori ọrọ wipe awọn kan nilu Calabar nfẹ ki nwọn da Ipinlẹ Ila Orun ati Ipinlẹ Ariwa (ni Oke Ọya) si ọna meji tabi ju belọ

(Wo yoku loju ewe karun)

## Moto Olopa Pa Iyawo Odejinmi

IBADAN—Aru abiyamọ ni o ṣe gbogbo awọn ara Ibadan ti nwọn ngbe Ekotẹdo nigbati nwọn ri oku abiyamọ alarede kan ti o ntọmọ lọwọ ti orukọ rẹ njẹ Theresa Ọdẹjinmi ti ọlọpa kan fi moto pa ni apafọn ni ẹnu ọna ibiti o gbe ti nsiṣẹ ninu redio alaworan.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa iku alarede na, a gbọ wipe bi o ti ṣiwọ lẹnu iṣẹ ni alẹ ọjọ kan ti ni o nduro de moto-tas (taxi) lati gbe lọ sile ọkọ rẹ ni Mọkọla, ibẹ ni moto ọlọpa yi ti wa kọlu u, ti o fọ lori.

Awọn ti nkan na ṣoju wọn ni ẹniti o nwa moto na ko feni ṣeji, nṣe lo bẹrẹsi sare lo fẹfẹfẹ; nibiti o gbe sare lọ na ni o tun kọlu Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni Matthew Daranọla, on na fara gbọgbẹ, o si wa nibiti o gbe npọka iku nile iwosan nisisiyi.

A gbọ wipe ti ko ba si awọn alanu ti o nwa ọkọ moto na ko ba salọ bamu-bamu, nitoripe moto ayọkẹle ni awọn alanu na mu ti nwọn fi sarẹ tẹlẹ ẹ.

Nwọn ti sin oku Theresa na ni iroẹ ijẹta, gbogbo enia pataki pataki ni nwọn si wa si ibi isin-isinku arabinrin na ti nwọn ṣe ni Ṣọṣi kan ni Ekotẹdo.

Ọmọ ikoko oṣu mẹfa wa lọwọ arabinrin na ti o ntọ lọwọ ki o to pade agbako yii. Ọlọrun majẹ ki a rin lọjọ ti ebi npona.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Oku—Ina

Boya ẹnyin ọkawe mi ti ẹ jẹ Imale ati ọmọlẹhin Krisiti le fẹ binu si mi diẹ nipa ọrọ INA ỌRUN APADI ti mo fẹ fẹnu kan diẹ ninu ọsẹ yi, ẹ jọwọ ẹ maṣe binu si mi, ọrọ lo ko mo ko moro wa.

## Kayefi

Mo gbọ wipe gbogbo awọn Lemọmn Eko Mọsalasi Forobe, Ereko, Idumọta, Ẹpẹtẹdo ati ti Salvado ni nwọn dorikodo nig'ati nwọn gburo wipe awọn ọta Ọlọrun kan jalu itẹ-oku, nwọn si hu awọn oku, kan jade ni Sare.

Eleyi na mọ si ṣe emi Ayiluka ni KAYEFI (bi ede awọn ara Ilọrin) ṣugbọn kayefi ti o wa nibẹ ni wipe ina-jannamọ ko si nibi kan ju inu aiye yi lọ. Emi ko wipe awọn ọta Ọlọrun ti o jalu itẹ oku ti o mbẹ awọn oku laṣọ jare awọn oku awa ara wa ti o ku nilẹ ni mo fẹ ṣe waasi fun wipe ki a ṣora pupọ Iku mbẹ alubuntu! Bi a o tiṣe ku ati ibiti a o gbe sun si ni a ko mọ. Iku mbẹ alubuntu.

## Olowo Ojiji

Kinni o wa fa ọrọ awọn ti nwọn nhu oku kiri yi o? Mo gbọ wipe laipẹ yi ni awọn kan nhu oku kiri ninu itẹ, ti nwọn bọ awọn oku laṣọ -mo gbọ wipe nwọn mbẹ awọn oku yi laṣọ lati fi wa owo-ojiji ni.

Irọ ni, otitọ ni, awọn ara Eko ni nwọn bọ aṣọ owo iyebiye kan lara oku kan ni Ẹkule Abari boya ninu itẹ oku Imale tabi ti awọn Onigbagbọ ni emi ko mọ, ṣugbọn awọn ara Eko nri diẹ ki nwọn to fi kun.

## Olowo Ereko

Ọrọ awọn ọta Ọlọrun yi ni o jẹki nniran awọn ọrẹ mẹta kan ti nwọn fẹ di Olowo ojiji ni opopo Agoro mọ i reko Idumọta ti nwọn lọ ya MAJẸ-AJA (owo—e'e) fun baba OMIṢAṢEGUN wipe ki o ba wọn ṣe agbo-ẹda owo, ti nwọn ni ki nwọn lọ mu nkan etutu ni mẹta mẹta wa, eiyẹle mẹta, igan aṣọ mẹta, igba mẹ'a ati ikoko mẹta mẹta. Mo gbọ wipe baba onişegua wọn na si nko ina mọ ikoko-agbo wọn na lọwọ.

## OMo Meji

Ọrọ owo-oiji le pupọ, bi ko ba ko enia si ijangbọn ninu i oluware ku lojọ aipe. Gbogbo awọn obinrin. AWỌN IYA ỌMỌMEJI DAWO SILẸ.

Mo ro wipe awọn Ọlọpa sinmi wahala a nwa ọmọ kiri nilu Eko ati ti Ibadan diẹ nigbati rogboyan ti de lọna Ikorodu, Shagamu de Ibadan, A ko gbọ wipe nwọn nwa ọmọ ti nwọn junu kiri tobẹ mọ. Nwọn ni awọn kan nlo awọn ọmọ fun etutu obi ti nwọn ngbin loko, awọn miran lati ṣẹṣo ṣugbọn ọrọ wọn na ko ye mi.

## Isinku Jibowu

Ẹnikẹni ti o ba de ibi isinku ologbe Sunmbọ Jibowo; aburo adajọ-agba Olumiyiwa Jibowu ti o jalaisi ninu osẹ ti o kọja yi. Isinku Ologbe na duu pupọ. Lati Ṣọsi Breadfruit ti nwọn gbe oku rẹ lọ ni gbogbo awọn ọlọpa ti ba awọn ẹbi, ọrẹ ati awọn alabakẹdun de itẹ ni Ikoyi' ti awọn enia si nkọrin aro.

Awọn ọmọ ologbe na ati aburo rẹ se bẹbẹ fun un gbogbo ẹsẹ awọn ẹgbẹ Afenifẹre ati awọn Ẹgba ile ati toko ni nwọn si pe sibi isinku na.

Sunmbọ Jibowu Orun re o!

## Omo Olowu

Mo gbọ wipe awọn Ẹgba ti sọ awọn idile ti nwọn ni lati ma jẹ Ọba Olowu ni Abẹokuta di idile mẹfa nisisiyi, ninu wọn ni idile Otilẹta ati Amọroro w... Mo dupẹ mọkan-mọkan ni Oye nkan enia, oye Olowu le kan emi na nitoripe idile baba baba iya baba mi wa ninu awọn ti nwọn darukọ na.

Ayiluka niyi, ọmọ Olowu oduru, ọmọ Ajibọṣin, ọmọ Aromatayi. Anlugbuwa a gbemi o!

## Awon Egbe NPC Bu Enu Ate Lu Oro NCNC

( O bẹrẹ loju ewe kẹrin )

A gbọ wipe ni Enugu ni ọsẹ ti o kọja ni Ọgbẹni J. U Akpabio tiṣe minisita alamojuto eto ẹkọ ni Ipinlẹ Ila Orun ni gbogbo awọn ara ilu on ni Calabar ti faake kọrun wipe a fori a fọrun awọn, fẹ ki Ijọba da Ipinlẹ awọn ni Calabar fun awọn ati pe ọna mẹrin ni o yẹ ki nwọn da Ipinlẹ Ariwa si lọdọ awọn Hausa lọhun.

Gbara ti awọn ọmọ ẹgbẹ NPC, ẹgbẹ olomi ti gbọrọ yi, ni nwọn ti tutọ soke ti nwọn foju gba a.

Nwọn ni ki olukuluku fi tirẹ ṣe tirẹ, awọn ko fẹ ki nwọn ge ilu awọn si meji rara, ambọtori on a mẹrin.

Ọkan ninu awọn Olori ẹgbẹ Olomi na, Alhaji Abdallah, ni Ọgbẹni Akpabio njowu iyi ati ọla ti o wa l'Oke Ọya ni. O ni ṣe o ri wipe ko si daru dapọ nilu awọn bi ti ilu ibomiran. O ni nkan ti Akpabio ati awọn ọmọ lẹhin rẹ ba fẹ ki nwọn fẹnu wọn sọ, awọn ko ni ge ilu awọn ke'ekele.

Sọrọ-sọrọ ninu ọmọ Yoruba kan ti o gbọrọ Alhaji Abdallah na ni Kaduna ni awọn oṣelu yi sọ Ipinlẹ Iwọ Orun di WERE DUN wọ, KO ṢE BI LỌMỌ, o ni ṣebi awọn ọmọ oṣelu mejeji yi ni nwọn so ipanpa pọ, ti nwọn gba awọn ara Benin mọ Urhobo kuro lọwọ Yoruba. Ọrọ re o!

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

# Ikede Egbe Olomo Tuntun

## Laii Owo Akowe

Ẹyin ọmọ iya mi lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba, a ṣe ikede yi fun onikaluku yin lati mọ daju pe ẹgbẹ ọlọmọ titun ti a da silẹ nṣe iṣẹ ribiribi fun idagbasoke ilu wa ( Nigeria ) papa pe ki iya ma le jẹ awa ti a jẹ ọmọ Yoruba kakiri ni gbogbo agbaiye, nipa ọna airiṣe, aini imọ ẹkọ to, iṣẹ owo ṣiṣe tabi inunilara ati oniruru ohun miran ti a ko le fi ẹnu darukọ.

A ko mọ iru ewu eyi, tapọnle ati ọla ti Ọlọrun fi wo wa, anṣiṣe Agutan-Inaki kakiri, ẹniti o ti nriṣe di alairiṣe, ẹniti o ti nwọ ẹwu olowu di ẹniti o nwọ aṣọ teru, ati nje pẹlu iyawo ati ọmọ di eti, ile aiye nsorikodo n ewo o ẹmẹ nlọ afe nlọ a ndi iho, kini awa fẹ mu.

Ki a ma mu ofo, ki a ma rin ofo ki a si ma p'ofo laiye wa, ki a ma ba di ẹni-ẹhin ati ẹni igbagbe, ki ito ọli ki o to wa ati awọn iran wa to tun mbọ lẹhin ki iya ma si le jẹ wa ati awọn na pẹlu, idi eyi ni awọn ọjọgbọn ile aiye se dide lati gbe ẹgbẹ yi dide, anfani wa nibẹ pupọ fun iwọ ati emi ati fun iru ọmọ rẹ.

Olowo nmu biya ya a, o n jẹ irẹsi pẹlu ẹran ẹlẹdẹ, iran tolotolo nṣe epo ati ororo ninu ikoko ṣin, o ngun mọto, Tẹlifiṣọnu nke gbo o ninu palọ rẹ, iwọ ati emi nmu burukutu kikan, a njẹ panla ati ẹfọ olu ti o nhu lati inu igbo jadẹ wa, a nwo jigi dipo Tẹlifiṣọnu, tani ko fẹ lati dabi olowo tabi lati ṣe bi olowo ti nṣe tani ko fẹ lati de ilu Oyinbo tabi ki o ran ọmọ rẹ lọ si ilu Oyinbo ninu iwọ tabi emi, tani ko fẹ lati kọle, dajudaju iwọ ati emi nfẹ be ẹ. Ki Ọlọrun ki O ran gbogbo wa lowọ o (Amin).

Ẹ ma ṣe jẹki a sọ ara wa di danasungbo, ẹ maṣe jẹki a sọ ara wa di aṣọ ẹgbin, ẹ maṣe jẹki oju ọ a wa wọmi lọ, ṣugbọn iwọ ati emi ọna wo ni a le gba lati fi ṣe eyi ki o ma le de ba wa?

Mọ daju pe ọna toya ni lati wa di okan ninu awọn ẹgbẹ olọmọ tuntun, ki o si foruko silẹ pẹlu igbagbọ ati aiṣiyemeji. Fi iwe ranṣẹ tabi ki o wa fun ara rẹ si ọfiṣi Olotu agba ẹgbẹ ọlọmọ tuntun ti ẹreka ti at ile ti Eko ti ẹka rẹ wa ni NO. 68B Jebba Street East, Ebute Metta, tabi ile iṣẹ ẹgbẹ na ti o wa ni NO.139, Igbosere Road, Lagos. Ẹgbẹ ma dara pupọ o, maṣe jafara.

# Olotu Obote Koba Ara Ilu Uganda

LONDON— Ọrọ ni ko mo ro wa. Ọgbẹni Miltoh Obote, Olotu ilu Uganda ti o ṣẹṣẹ gbe iyawo alarede lupẹ yi ko bo awọn ara ilu rẹ ti awọn Oyinbo ala ru fẹ ṣe iṣẹ ti o npa awọn ara ilu na

Gẹgẹbi irohin ti o gbọ, awọn ẹgbọ alaini ilu Oyinbo kan ti orukọ baba ẹgbẹ na nje Ọlọla Sir Herbert Barber ti nwọn da a silẹ ni ilu Soutaport lati GBOGUN TI EBI ti o npa awọn ara ilu Uganda.

Gbogbo owo ti nwọn da lati ko lọ se iranlọwọ fun awọn ara Uganda jẹ ẹgbẹrin ponun (£8,000) ṣugbọn nigbati awọn gbọ wipe ẹgbaje ponun (£14,000) gbako ni awọn ara ilu Uganda na fi n igbeyawo olotu wọn, awọn ọmọ ẹgbẹ alanu ilu Oyinbo ni ki nwọn ma fi owo anu na ranṣẹ si wọn nitoripe o yẹ ki awọn na le ma ṣe itọju awọn ara ilu wọn ti ebi npa lojojumọ.

# Eleti—Ofe Da'raba

**Ẹ ka oro ỌLOFINTOTO lori Aso Aloku Bosikona ni oju ewe Keta.**



**Awon omo iyawo alarede ti nwon nte le iyawo lehin ni e nwo ninu aworan yi.**

# Shakespeare After 400 Years

LONDON — Today (April 23rd) is ST GEORGE'S DAY, and it will be observed as 400 th aniversary of William Shakespeare's birthday a new Shakespeare Centre will be opened at his birthplace at Stratford-upon Avon.

## Shakes' Workshop

Modern in design, but harmonising with its surroudings the Centre will provide acommodation for the Shakepeare Birthplace Trust, and for the books manuscripits records and other material, which the Trust has accumulated since it was set up in 1847. The Centre will comprise a library, combining the collections of tha Birthplace Trust and the Royal Shakespeare Theatre at Stratford, a reading room for reseacrh, and provision for lectures and exhibition.

Transfer to the new home should be comleted early in the New Year. Thus a well - equipped Shakespeare and workshop will, in the new Centre be brought together in one place, working in close co-operation with the Royal Shakespeare Theatre, the Shakespeare Institute, the British Council, and with universities and scheols boths in England and overseas.

## World-Wide Appreciation

Director of the Centre and of the 1964 Shakespeare Anuiversary Council is Mr. Levi Fox, who has been directing the work of the Shakespeare Birthplace Trust for some years. Mr Fox says that appreciation of Shakespeare is not just a sentimental feeling about the poet and his work, nor is it merely local. It has grown enormously and at many levels, since the tercentaudry celebrations in 1864, from playgoers and children to scholars all over the world; For example, in Latin a translation of the poet's works in six volumes is being prepared to mark the 400 anniversary of his birth.

A quarter of a million visitors visit Shakespeares birthplace every year, more than half of them from overseas.

The Quatercentenary Festival at Straford-upon-Avon opens on April 23 1964, and will be diveded into highlight periods with in each of which there will be a mixed bill of fare of commemorative activitiss. An exhibition will illustate the life and career of Shakespeare against the background of his time.

## Medical Museum Techniques

LONDON— Preparing parts of the human body for display in medical museums may sound a grim art but it is an important aid to medical science and a direct help in training doctors.

Studying this art in Britain is Mr. R. I. Okpa of Lagos University, who will spend six months at the Royal College of Surgeons' Museum in London.

"This Museum is probably the best in the world. There is nothing elsewhere to compare with it and people from medical school all over the globe are constantly visiting it for advice," he said to our Correspondent in an interview conducted amidst many exhibits of preserved human organs.

Mr. Okpa, who is Tutor Presector of Anatomy at the Lagos University Medical School, hopes to help in setting a full scale medical museum when he returns home.

# Nigeria to Join Parade at Dartmouth Centenary

LONDON—Nigeria will be represented in force at the Centenary Ceremony of the Royal Naval College at Dartmouth tomorrow, Sunday.

In the march past of saillors and officers from Britain and nine overseas countries will be fourteen cadets and three sub-lieutenants from Nigeria.

Many thousands of cadets from every Commonwealth country and of many nationalities have passed through the Dartmouth College in southern England.

# British Education Lecturer to Tour Nigeria

LONDON—Mr A E G Pilliner, Lecturer in Experimental Education at the University of Edinburgh, is spending two weeks in Nigeria at the request of the West African Examination Council. Mr. Pilliner's tour has been arranged by the British Council.

He will visit Port Harcourt, Enugu, Ibadan, Kaduna and Lagos and will address groups of principals of schools, secondary schools teachers and examiners of the West African Examinations Council on the testing of attainment in English, arithmetic and other subjects included in examinations at School Certificate level.

Since 1949, Mr Pilliner has been responsible for research at the University of Edinburgh into the construction of Moray House tests, including 11x tests used extensively in Britain by education autheorities in selecting children for secondary courses at the end of their primary school education. He is also responsible for courses in experimental education given to graduate students reading for the Diploma in Education, the honours degree of Bachelor of Education and for Ph D student working in the field.

While in Lagos, Mr. Pilliner will conduct a course of instruction for a selected group of examiners of the West African Examinations Council.

An expert of wide international experinence, Mr. Pilliner has contributed extensively to the Journal of Educational Psychology and has worked as U.N.E.S.C.O. expert in Israel concentrating on the difficulties of educating children in a community with diverse cultural background and with the teaching of English as a second language

Mr Pilliner leaves Nigeria for Accra on December 2 to carry our a similar programme of instruction.

## Loya Awon Ara Loko

(O bere loju ewe kinni)

Gegebi iwe ipejo ti awon osise Loko fi pe Loya Emejulu lejo, egbaa ponun (£2,000) sarai ni nwon ni awon na lori re fun eko loya ti awon ni ki o lo ko ni iwon nkan bi odun merinla sehin.

Nwon ni adehun wipe bi loya yi ba ti de o ni lati se akowe egbe awon fun odun meta ni awon jo se, sugbon nigbati loya na ko eko tan, nse ni o fonmu mo awon lowo. O ko lati sise lodo won.

Nwon ti wa lenu ejo na tipe sugbon ninu ose yi ni awon omo egbe osise Loko pelu Loya na tun ru ara won lo si iwaju Adajo agba ninu Kotu nla kan wipe awon ti pari oro na.

Nwon se alaye wipe awon pari re si wipe ki Loya Emejulu ma san owo na diedie, sugbon ki o to ma san ogbon ponun lososu, ki o ko san ponun marundinlogorin (£75) ni oni sola, ki o si san ponun mejileladota ati sile mewa (£52 . 10) owo irin ese fun awon osise Loko.

## Jaja Wo "Sokoto Ija" Pelu Alhaji Bamali

EKO—Bi ko ba si sure ti okan se ni awon Minister alomojuto oro ilu okere, Ogbeni Jaja Wachuku pelu ekeji re, Alhaji Nuhu Bamali, ko ba wo 'sokoto ija' nwon ko ba tun soko oro si ara won lori ise a alo pari ija ti Olotu Ijoba wa ran Alhaji Bamali ti o fe je fun awa ara ilu, ti o pe awon oniwerohin, fun ki nwon le te oro na sita.

Ile ise won ni Ehingbet ni Alhaji Bamali ko pe ipade awon on'rohin na si, sugbon Ogbeni Wachuku ranse si i wipe on ni o ko ni lati jabo fun, ki o si gbase lowo on ki o ba enikan soro rara.

A gbo wipe Alhaji na ni Wachuku ko ni o ran on nise nitorina ko si ore wipe on jabo fun nibe. Were Alhaji na ti ni awon akowe on tete fi ero gbohuu so fun awon oniwe irohin ki nwon pade on ninu ile ti on ngbe l'Ooun Alasia lati gbo nkan ti on ba bo Addis Ababa.

Alhaji Bamali ni oju ko ti awon rara Jnibiti Olola Balewa gbe ran on lo lati lo ba awon ara Morocco ati Algerin ti nwon nja lori a'a-ile pari ija.

Alhaji na ni Jaja Wachuku kise oga on rara nitori ise o ni Minisita ni i, minisita si ni on na paap .

O ni iyoku oro ija na di osu ti mbo ki awon to ba won yanju re ni i'u Abidjan ni Ivory Coast

## Oro "Aloyun Kawe' Wa Ni Kotu

(O bere loju ewe kinni)

araye yan ale, Salifatu ni beni. Adajo na wa koju si gbobo awon ti o wa gboro ni kotu, o ni bi awon iya won ba ti ba won lorije tan, won ma wipe ki Olopa gba won. Adajo ni awon iya buruku le ki nwon mu lo si ile alatori, ki nwon bo won nidi daradara.

Bi e ba le se ooraye lo si ko'u awon Olopa l'Eko lotunla ojo Aje, eo le gbo iyoku ni ekunrere

## Ijoba Ilu Congo

(O bere loju ewe kinni)

nwon ti nwon mole, sugbon nigbati ariwo awon Olotu oga won ni Moscow po wipe ki nwon da won sile po, awon ara Kongo da won sile, nwon si pase wipe ki awon Oyinbo na kuro nilu awon logan.

A gbo wipe awon olopa ilu na tun ti oniwe irohin ara ilu Russia mole lori iwe ikede iku Ologbe Lumumba ti awon ba lowo won Nwon ni nwon tun fe ko wahala wo ilu.

## NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

CHRISTMAS SHILLING—FUND, 1963.

Depositors in the Christmas Shilling Fund are hereby reminded that in accordance with the regulation governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Mouday 2nd December 1963.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on producting of his/her Passbook. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned; such application to be accompanied by the depositor's Passbook, for interest to be entered up.

Withdrawal for the year will close on the 31st December, 1963, and depositors who fail to withdraw on that date cannot do so until next Christmas.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositor's surnames on the date shown hereunder and the depositors who fail to apply on the prescribed dated shall not be attended to until Monday, 9th December, 1963;

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | A | Monday | 2nd | December | 19[illegible] |
| B | to | H | Tuesday | 3rd | " | " |
| I | " | N | Wednesday | 4th | " | " |
| | | O | Thursday | 5th | " | " |
| P | " | Z | Friday | 6th | " | " |
| A | & | Q | Saturday | 7th | " | " |

For the year 1964, deposits will be taken as from Thursday 2nd January, 1964.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.

ARA MIRAN TUNDE ;

## Awon Huku - huku Gbode L'Eko

EKO— Ara miran tun wo ilu Eko, a tun gbo wipe awon enia kan oku oloku ni oku ti nwon nhu nite oku kiri, ti nwon bo won laso, ti nwon si nyo ifun won ndana sun won.

Nkan ni Ite oku owon Imale ni oke suna nigbati awon ara adugbo na taji anjo oru ti nwon ri ti na njo bilabila ninu ite oku ar je awon enia kan ni nwon ti wo ite oku ti nwon hu awon oku ojo keta jade, ti nwon yo okan ti nwon fo lo lara won

Popoola Kuku ati Taofiki Lasisi ni oruko awon oku ti nwon hu jade na nje, awon dokita Oba ti m ki nwon sin ajoku awon oku na pada si koto koto, ki arun lukuluku ma le wolu.

## E Ka Oro Awon Oyinbo India

Loju Ewe Kinni

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor; (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, Box 467